Chief Secretary to the Government

IWE ADEHUN GẸSI PẸLU ỌBA DOSUNMU HA JẸ "ARAMU" BI?


# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. VI. No. 281 SATURDAY, JUNE 30, 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.



## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[*A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.*]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

NIGERIAN SECRETARIAT 11 JUL 1928 LAGOS

### EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[*Fun Atọsi lailai ati titun.*]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si nje ki o ri aye wu arun mi silẹ.


A. Desorb...


LOOK FOR
THE PORTRAIT
OF
Dr Earl Sloan
SLOAN'S
N&B
FAMILY
LINIMENT
Trade Mark Registered
KILLS PAIN
Medicine Dealers
RELIEVES
Rheumatism
Neuralgia
Sciatica
Sore Gums
Sore Muscles
Sprains
Strains
Swelling
Tender Feet
Toothache
Ulcerated Teeth
Stiffness and
Soreness after
Severe Exercise
General Directions
for External Use
TO STOP
YOUR ACHES & PAINS
SIMPLY USE
SLOAN'S LINIMENT
Sold by all Dealers.
Wholesale: Fassett & Johnson Ltd
Clerkenwell Rd. London Eng.

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Oke-ere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor.*

## GBOHUN-GBOHUN.

KA ṢI MA WO!

Itumọ Agbọsọ ti a tun ngbọ lọtun losi nisisiyi pe a ki yio fun *Prince* Eṣugbayi Eleko laye lati bọ wa si Eko fun ẹjọ rẹ; agbọsọ ni a mọ eyi si, nitorina a ko ni ti ṣiwaju ẹlẹdẹ; ohun to ṣoro loju egun awọn ti bo o

IROHIN AYỌ KURO LAWADA.

Oporo ọti ati onjẹ ni a gbọ pe awọn ara Ibadan fi yọ ayọ jijare ti Eleko jare Apili ṣe lọsẹ to kọja ni ilu Ọba, pō pō pó ni ọti ndun lọtun losi

DUNIYAN—LABARI.

Lati ọwọ KEKERE AWO.

IGBA-GBO!

Erin ki ifọn ki ọmọ rẹ tun fọn ni ko jẹki a ni arafi ọrọ kan ni jẹjọ ninu ọrọ Ọba wa to bẹ 'lẹ gija ni 'lu lọjọ Atalata ọsẹ to kọja, ni iwọn igbati a gbọ wipe " Meigida " wa fẹ dabira lori iro na ninu iwe ọsẹ to kọja.

ELEKO FI GBỌRỌ JẸ 'KA, O PEGEDE.

Ilu rọgirigi lọjọ Atalata ọjọ 19 oṣu yi nigbati Lọya Eleko fi waya oju-omi lakalaka ṣọwọ si Eko pe Eleko fi gbọrọ jẹ 'ka ni *Privy Council*, o pegede —eyi ni pe o wo ẹjọ arotunro rẹ jẹ, eyiti awọn ogunna gbongbo ti nda 'tọ lẹnu igbin—Adajọ Lord Chancellor, Lord Buckmaster, ati Lord Warrington, da fun u pe o jare ẹjọ na, nitorina ki nwọn fun ni owo irin ẹsẹ lohun ati ti ilẹ yi.

Nigbati waya fọnka silu, o di b' o lọ o ya mi. rẹrẹ o di le Makọli, ẹniti ko le rin ni ki ngbe on, gbogbo ilu lomode lagba, lokunrin ati lobinrin bẹrẹsi pariwo ge e pe ẹjọ Eleko jare gbangba, oju ti alabosi rikiṣi pin, bẹni olukuluku nfi ijo dabira, gbogbo rẹ ndun yungbu bi igbati a ba da ṣuga mọ oyin—eyi fihan gbangba pe bi igi npọn 'gi mọ 'gi lailai ni nwọn o ma fẹ Eleko ọmọ Alade na—*La-ilaha-ila Allahu*, ẹmi awọn Onidajọ wọnyi agbo a tọ ọ.

AWỌN ỌMỌ 'BA DOSUNMU.

Awọn ọmọ-ọba Dosunmu fi waya ti nwọn papa ṣọwọ si Lọya Eleko ni ilu oyinbo lọjọ Atalata kanna pe awọn ba a yọ fun ogun ọrọ Eleko ti o ja gun molu.

ILU KỌMITI

Awọn Ẹgbẹ Abibu Oki Balogun, Ilu dabira ni ile Oki lọjọ Atalata ti ogidigbo labari Eleko yi wo 'lu nipa ayọ ẹjọ yi ti o ṣoju rikiṣi-ile rikiṣi-ode, ayọ ọjọ na kaseta bo ti dun mọ ni iyẹn ẹnikeji—ayọ abara tintin! ki Ọlọrun jẹki iyoku ṣoju gbogbo wa.

BARIKA O!

Awọn ẹnitl a gbọ wipe nwọn lọ yọ fun Eleko ni Ọyọ nigbati labari de lọjọ Tuesday ti pada de lọjọ Alamisi ọsẹ to kọja—BARIKA O! ṣe alafia ni olowo wa mbẹ? A tanına pe bẹni *Alihamdu-li-Lahi.*

ELEKO D' OṢU OLE KENKA.

Lọjọ ti waya de lati ilu oyinbo pe Eleko JARE ni oṣu le si sanma, eyi fi han wipe lati ode ọrun ni Sati ti gbe ade rẹ ka a lori—Enia ni nbinu Ọlọrun Ọba ki binu walai!

ỌMỌ ỌBA AKAMỌ-ẸKUN.

A ki gbogbo nyin patapata lati oke de 'lẹ a ko da ẹnikan si fun orire ni 'ta awo ti Ọba wa Eṣugbayi Eleko ti o ṣe ni ilu oyinbo ni ọjọ Atalata ijẹjila, ori baba nyin yio gbe nyin lọrun, Ọba adakẹ dajọ mbẹ walai!

Bẹni a si tun ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ nwọn ku wahala ki a fi gbogbo ohun le Sati lọwọ, ọba a fi otitọ inu tu ẹru ika palẹ.

WAYA LATI PORT HARCOURT.

A gbọ wipe awọn ẹgbẹ *Democratic Party* ti o mbẹ ni ilu Port Har-court fi waya ṣọwẹ si ilẹ yi larin ọsẹ to kọja pe awọn ba ilu yọ gidigidi fun are ti Ọba wa Eleko gba.

## IPADE BOMBATA.

O ta si wa leti finrin bi ẹnipe Ipade nla pataki kan yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ "Dẹmọ" ni ile Afari-ogun lọjọ ti ko pẹ yi, aṣa re ẹiyẹ ngb' ẹiyẹ fo, ki Ọlọrun mu ọjọ ro.

## MISCHIEF AGAIN.

It is being rumoured that the Administrator of the Colony, Major W. Birrell Gray attended a meeting of men and women of the Ibikunle Group at the Iga on Wednesday, when he informed them of the Judgment of Eleko' Appeal, and added that although the Prince has won the Appeal, his case will be tried at Ọyọ, but the Prince will never come to Lagos anymore.

We shall be glad to publish an official denial of this story ; signed either by the Administrator himself or any authorised officer of the Government under him, in Justice to himself.

There are some mischievous person who are still bent on fanning the flame of political discord. But as far as the case of Prince Eleko is concerned His Majesty's Privy Council is always open to His Majesty's subjects, throughout the empire, for the hearing of Appeals from the British Colonies and His Majesty's Dominions over the seas—L.D.N. 22/6/28

## STOP PRESS.

As we go to press, we are informed authoritatively from Ọyọ, that, on Thursday, the District Officer, Ọyọ and a European Police officer called on PRINCE ESHUGBAYI ELEKO at Ọyọ and told the Prince that he will not be permitted to leave Ọyọ.

The officers in the protectorate in the Southern Province of Nigeria are under the control of His Honour the Lieutenant-Governor, S.P., who certainly, could have given no such instructions, we are sure.

If the message be true, why then should British officers,—whose prerogative it is not to decided such a question,—molest an innocent African British subject in this manner ?—L.D.N. 23/6/28.

## OWO-ORI.

Ibẹrẹ oṣu ti a o bọ si lọla yi li a gbọ wipe nwọn o ma gba owo-ori gẹgẹ bi a ti wi lọsẹ to kọja : Awọn ọmọ Eko ti a gbọ wipe o nwa iṣẹ lọ si ile iṣẹ ti Ijọba ṣe fun owo-ori na nwọn fẹrẹ to ẹgbẹ run, eyi fi han gbangba wipe ko si iṣẹ ni ilu gẹgẹ bi igbe ti a nke fun Ijọba Igẹsi, ati gẹgẹ bi a ti sọ wipe ki nwọn da iṣẹ pataki silẹ, ṣugbọn sibẹsibẹ a ko ti ro wipe Ijoba ṣe ho o si i ! ọran re bẹ, a o ma wa o ni aja ngbo.

## EJI GB' ỌJỌ.

Ojo ti o rọ ni alẹ ọjọ Alaruba ọsẹ to kọja titi di ọsan ọjọ keji rẹ fẹrẹ hu 'ku ọlẹ tobẹ ti a fi gbọ wipe o wo ile kan ni adugbo Anikantamọ.

## JAMAT-ALALUKURANI.

A gbọ wipe awọn Jamat Alalukurani gbogbo lọ yọ fun Makọli ni ile rẹ ni ọsan ọjọ Jimọ ijẹsan, lẹhin ti nwọn ṣe isin tan ni Mọṣalaṣi—ayọ are ti Eleko jẹ, nwọn ṣe adura fun Makọli gidigidi ati gbogbo awọn ẹmẹwa rẹ, nwọn si tun ṣe adura fun Eleko papa pe Ọlọrun jẹ ki o le pada bọ wa ba wa pẹlu salamu ! salamu !!

## A-PỌN B' EPORẸ GỌRUKỌ Ẹ.

Ko si bi o ti ri ni ijo arakuyamu ti awọn enia nla mọra ni Iga oloye Oluwa lalẹ ọjọ Atalata ti a ni ọba Eleko jare—Pẹtẹsi Iga Oluwa dabi afin Ọba ti oluwarẹ ba nwo lokere ; Ha ! aje ku 'kalẹ, ki Oluwa jẹ ki ẹmi lo Iga yi dopin, a si tun ki ọ ẹ ku ayọ abara tin-tin na !

## IWE ARAMU DORIJI TAGBO KA'LU.

Nigbakugba ti iwe ba tẹ ilu lọwọ nipa bi ọran Eleko ti nlọ si ni ilu oyinbo ni awọn "Gbẹbọ" ma nṣẹfẹ pe iwe-aramu lo de, ati pẹlu Makọli npurọ fun wọn Lẹhinigbẹti ni—ṣugbọn ni ijejila ti waya ro winrinrin bi ago pe "Olwo Ọba" wa jare, idi wọn d' omi ẹlomiran fẹrẹ le ṣu si ṣokoto, kẹkẹ wa pohun mọ awoko lenu fuja ti a gbọ wipe nwọn tun nṣe nisisiyi ni wipe Eleko ko ni de, a si rope awọn ẹniti ko kan lo nwi bẹ kiri ilu, kekere lo npe ike awe !

## TIRẸ TO BẸ OJU BẸ LỌ OṢUMARE JARE OJO, OJU TI ALABOSI.

Ọpọlọpọ awọn ilu pẹpẹpẹ li a gbọ pe nwọn nranṣẹ wa ki Makọli "Ejo-ni-igboro" pe o ku aforiti o ku ayọ Ọlorun doju ti alabosi oṣumare jare ojo—Eṣugbayi Eleko jare ni ilu Ọba na.

## IPADE AWỌN ONIWE-IROHIN.

A gbọ wipe ni owurọ Satide to kọja, oyinbo ọgagun W. Birrell Gray mu awọn oniwe-irohin ilẹ yi bi Ọgbẹni E. S. Ikoli *The Nigerian Daily Times* Ọgbẹni T. H. Jackson, *The Lagos Weekly Record*, Dokita R. A. Savage, *The Nigerian Spectator*, Alagba Kitoyi Ajasa, *The Nigerian Pioneer*, Ọgbẹni H. Antus Williams, *The Nigerian Daily Telegraph*, Ọgbẹni J. A. Oluṣola, *The Lagos Daily News*, Ọgbẹni S. H. Braithwaite, *The Nigerian Advocate*, Ọgbẹni I. B. Thomas, *Akede Eko* ati Ọgbẹni E. A. Akintan, *Eleti Ofe*, lọ han oyinbo Ọgbẹni Peterson akọwe *Times* ti o ti ilu oyinbo de ni lọlọyi. A gbọ wipe oyinbo na yio gba ọsẹ marun ni ilẹ enia dudu ati pẹlu yio mu ọna irin-ajo pọn lọjọ Atalata ijarun.

## ENMỌ NLA!

A gbọ wipe nwọn mu ole kan lapa adugbo Oke-popo loru ọjọ Monday nigbati ole Pokiti-igbọnṣe ru, ti o gbe ina pẹlu igbalẹ lọwọ ki a ṣa sọ wipe o ṣe gẹgẹbi awọn Agbe-pokiti ti o ngbe igbẹ loru, o wa fẹ gba oju fereṣe wọ inu ile, ki ọlọpa kan to ṣe kongẹ rẹ pe bi enia tilẹ fẹ gbe igbẹ, oju fereṣe ni nwọn ti ngbe igbẹ ; jẹbẹtẹ gbọmọ le e lọwọ, alalikuwa ofi fo Pokiti lo gbe da ni bi a ti yin iro na si waleti ni iyẹn o—ẹ o wa ri gbangba wipe jamba awọn ole da 'iye.

---

## ORI IV.

## IṢẸ.

(*Translated from "Character by Dr. Smiles"*).

APA KẸTA.

---

Ani, isimi papa ko ni adun, aiyaṣebi a ba ti ṣe wahala ki a to ri i. Bi a ko ba ṣe iṣẹ ki a to ri isimi, a ko ti ra isimi.

Iṣẹ ni lati ṣiwaju ki iṣẹ tun kẹhin ki isimi wa jẹ ohun ti a fi abọ fun ; ṣugbọn isimi laisi iṣẹ ko ni adun kan ju ti aje poholo lọ. Aiye ko le ṣai su ọlọrọ ti ko ṣe iṣẹ kan, bakanna bi yio ti su otoṣi ti o ya ọlẹ ti ko ni iṣẹ kan ti o nṣe, tabi ti o ri iṣẹ ti ko ṣe.

Awọn ọrọ ti ọlọgbọn ma mọ ero ọkunrin alagbe kan—ẹni ogoji ọdun, ti o si di ẹkẹjọ ti o nwọ ẹwẹn, ni ile ẹwọn Bourges ni France—ko si apa ọtun rẹ ni iba jẹ ti gbogbo awọn ọlẹ enia :

"Ti ijọun tan mi jẹ ; ti isisinyi nfi mi lapẹ ; ti igba ti nbọ ndẹru ba mi"

Gbogbo enia ati olori ati elese ni iṣẹ ṣiṣe ba wi. olukuluku ni ayekaye ti o ba wa ni o ni iṣẹ tirẹ —ati ọlọrọ ati otoṣi.

Ẹni ti a bi ire ti a si kọ, bi o ti wu ki o la ki o lu to, ko le ṣai mọ pe ọranyan ni ki on na ṣe ti on fun ire gbogbo enia ninu eyiti on papa njẹ. Ko le tan nidan ki ati jẹ ati mu ati wọṣọ rẹ, eyiti awọn kan nlagun ki o to ri, lọ lasan laisan ẹsan bi o ti tọ fun wọn.

Ara ọmọluwabi a kọ ki o joko ki o jẹun lajẹgbadun laiṣe abere ẹhin ibi ti onjẹ na ti wa.

Ki enia ya ọlẹ ki o ma ni anfani kan lara, ko ni iyi tabi ọla kan ninu. Ti awọn mari-majẹ enia ni ki nwọn ri ki nwọn jẹ wọmu-wọmu, ṣugbọn awọn enia ti ko gọ, awọn ti nlakaka ati awọn ti nfi otọ inu ṣe nkan mọ pe ka ri ka jẹ ṣa, ki iṣe ọna ti ọmọluwabi.

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

## IROHIN AWỌN IGBIMỌ ALATUNṢE ỌBA ALAPẸRU ỌLỌLA.

Nipa ija to wa larin Madam Odumusi ọmọ Ọba Alapẹru ati Ẹfunyẹla ọmọ Alagbe ti Ẹjina Ipẹru town o dabi ẹni pe Ẹfunyẹla nfẹ da ija silẹ ni Ile Ọba Alapẹru Ọlọla ọpẹlọpẹ awọn Igbimọ Ọlọla nla Lẹmọ, Ọpẹlẹ, Apena, Ajayi, Jọnu, Ọgbẹni Ọpẹodu, Ọgbẹni O. Shobodu, awọn Alatunṣe Ile Ọba Alapẹru ni yẹn, awọn ti wọn mu Ẹfunyẹla jade kuro ninu Ile Ọba Alaperu nigbati o nfẹ da ija silẹ ni Ile Ọba Alapẹru ọrọ na bi Ọgbẹni Akilesi Likọtun Ọlọla aburo Baba wa ninu pupo tobẹ gẹ ti o fi wa sọ ni ile wipe nkan ṣe loni ni ọjọ keji Ẹfunyẹla gbe atẹ aṣọ lọ kiri de Agbole Olugoke, nigbana ni Madam Oyebade sọ fun Madam Ẹfunyẹla pe on ko fẹ ki o tun de Agbole baba on mọ nitori o mu ohun ibinu wa si arin wa pupọ ki Ọlọrun Oluwa Olodumare ki o pẹlu Alapẹru ati awọn Igbimọ ati gbogbo ilu.

J. A. O. SHOMADE.

---

## IWE LATI ỌDỌ J. A. SHOMADE SI IJỌBA GẸSI NI EKO.

Mo bẹbẹ mo si fi oribalẹ fun ẹnyin Ijọba Igẹsi nipa ọran owo ṣile ti awọn Ijẹbu nṣe ọna ti Ijọba Igesi fi le kawọ awọn Ijẹbu ti o nṣe owo ṣile ni yi. Afi bi Ijọba Igẹsi le ran awọn Private tabi aṣiri Detective tabi Ọlọpa Inu ranṣe si Ijẹbu Rẹmọ ati nigbogbo agbegbe Ijẹbu Ode ki awọn Ọlọpa Inu yẹn ma wọ gbogbo Ile Agbẹdẹ ki awọn Ijọba Igẹsi jọwọ ba wa ma parọ awọn Ọlọpa Inu na ni ọsọsẹ ẹ ma jẹki ẹnikẹni ni Ile Aṣiri tabi ibi aṣiri rara nipa ọkan Agbẹdẹ ṣile ti wọn nṣe ni ilẹ Ijẹbu yio kakuro ni ilẹ wa bamubamu tabi patapata.

J. A. O. SHOMADE.

---

## ẸDA IWE ADEHUN LARIN ỌBA DOSUNMU ATI IJỌBA GẸSI TI A ṢE NI IJỌ KẸFA OṢU AUGUST 1861-ỌDUN KẸTADINIADỌRIN LỌHUN.

1. Ki Ọbabinrin Ilu Gẹsi le ni aye lati ṣe iranwọ, idabo, ati ipamọ awọn ara Eko ati ki o le fi opin si òwò ẹru ni Ilẹyi ati agbegbe rẹ, ati lati fi opin si awọn ogun p'aiye tun ti awọn Idahọmi ati awọn ẹlomiran ma nja nigbkugba lati ba le ri aye ko ẹru, Emi, Docemo, pẹlu imọran ati ifohunsọkan awọn Igbimọ mi nipasẹ ilana wọnyi, fi talọrẹ, yida, gbọjẹgẹ, mo si jẹri si ati fi, Erekuṣu ati Ilu Eko, pẹlu gbogbo ẹtọ, ere, amọna, ati awọn ohun miran gboggo ti o wa pẹlu rẹ tọrẹ fun Ọba 'binrin Ilu Gẹsi, awọn ọmọ ati irandiran rẹ lailai, ati awọn ere, pẹlu owo asingba gbogbo ti o wa kakiri

ti a fi da Ijoba Erekuşu ati Ilu Eko ni ọla pẹlu gbogbo ọla Ọba ti o wa nibẹ ni mo yọda patapata ni kikun ni ai fi ọkan sẹhin tabi pẹlu ikusinn. Mo si da majẹmu pẹlu pe tinutinu ati lai si idiọwọ kankan ni mo yọn la pe ni jẹjẹ ati aisi ikunsinu ni a o jẹ ki Ọba binrin Gẹsi tabi ẹniti o ba yan gba Ilu na pẹlu alafia ati aisi ija ni kiakia ; a o si ma jẹ ki awọn ara ilu Eko pẹlu amọna rẹ ma wa nibẹ gẹgebi ọmọ abẹsẹ Ọbabinrin na, wọn o a si ma gbe abẹ abo ọla, ade, idajọ ati ijọba rẹ.

2. A o jẹ ki Docemo ma lo Oye "Ọba" bi ilana Enia Dudu, a o si ma jẹ ki o ma pari awọ larin awọn ara Eko ti wọn ba fẹ ati pẹlu aye lati apili si ofin Gẹsi.

3. Ti a ba nyọda ilẹ, otitẹ Docemo ninu rẹ, yio jẹ ẹri pe Enia Dudu ko ni ẹtọ ninu rẹ, ati nitorina ao jẹ ko ma lo bi o ti ma şe ri,

Nitori adehun ifi Erekuşu ati ilu Eko pẹlu amọna rẹ torẹ ti a şe siwaju, Aşoju Ọbabinrin Gẹsi, se ileri, eyiyi bi Ọbabinrin Alaiyeluwa ba fi owọ si, pe Docemo yio ma gba owo ọdọdun lati ọdọ Gẹsi, eyi ti yio jẹ aropọ owo asingba ti o ma ngba ti a ba yọ inawo kuro nibẹ a o si ma san owo yi li ọna, ati ni igba ti a o şe ipinnu rẹ lẹhin eyi.

| | Their |
|---|---|
| Docemo | |
| Telako | x |
| Rocamena | x |
| Ọbalekow | x |
| Achehong | x |
| | Marks |

NORMAN B. BEDINGFELD, Her Majesty, ships "Prometheus."

Senior Officer, Bights Division.

W. McCOSKRY Acting Cousul.

*Nigerian Daily Telegraph* 25 & 26/6/28.

## ẸNI MABI TIRẸ A YỌ FUN ỌLỌMỌ

A ba Ọgbẹni M. B. Oshodi ti agbo-ile Akiyẹmi yọ fun ọmọ-binrin ti Iyawo rẹ agunlẹyinju fi talọrẹ lọsẹ to kọja a si tun ki ku inawo ti o şe ni ọjọ Atalata ọsẹ yi, *26th June, 1928*. Nigbati a fun ọmọ na ni oruko, awọn alagba ti a ri nibẹ ni : Ọgbẹni D. Ayọdele Bright, L. A. Ojo, S. S. Oshinde, S. K. Benjamin, Emanuel Oshodi, J. Macaulay, J. Ajiborọ, Ayọ Pereira ati awọn jakanjakan miran ti a ko ri aye lati darukọ.

Sikiratu Lai ni oruko ọmọ na, ki Oluwa ko da si fun awọn obi rẹ.—Amin.

ỌMỌ YAYI.

## Ẹ Ş'ASALATU F'ONIŞẸ ỌLỌRUN.

*SALALAHU ALAIHI WASALAM!*

APA KEJI.

LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*,

Mo bẹrẹ f'oji,

Awọn ẹlomiran ti ko gba ti Anabi Mọmọdu bikoşe ti Issa nikan ma nşọ wipe ipa, girimọkayi pẹlu ida ni Anobi Mọmọdu fi nmu awọn enia şe Musulumi lagbara, ati pe enia ti ko ba gba tirẹ, yio fi ida bẹ oluwarẹ lori, awa ri wipe ọrọ ẹgan li eyi jasi.

Nda o ! lati iwọn bi ẹgbẹfa ọdun tabi jubẹ lọ nisisiyi ti Anọbi Mọmọdu ti papoda nkọ o? Şe oku rẹ lo jinde lati Sare rẹ ni ilu Mọdinat ti o nfi ida ti nwọn nwi sọ wọn di Musulumi agbara ni gbogbo orilẹ-ede patapata ti o fi wa de ilu Eko yi ?

Awọn Ẹlomiran le ma so wipe ẹsin gbẹfẹ ni ẹsin—Imale, nwọn si ni anfani lati so yigi mẹrin ki Wahari si tun pẹlu ki Imale pọ pupọ larin wa. Awẹ ti Imale ngba, irun nigba marun-marun ti nwọn ni lati ma ki lojojumọ, Mọşalaşi ti nwọn ni lati ma para nigbagbogbo ati oniruru nkan miran ti sẹria ni ki nwọn şe lọna ti ẹsin, idaji eyiti awọn Kiriyo ko nşe kole jẹki awa gbagbọ wipe gbẹfẹ ni ẹsin-Imale.

Ati nipasẹ ti yigi mẹrin ati Wahari ti o tun şi-karun, awa ro pe ẹniti o ni obinrin meji, mẹta tabi mẹrin ti o si tun ni Wahari kan pẹlu gẹgẹbi ohun ti a nwi yi ni gbangba, ti Ọlọrun si bun unni Karufi lati tẹ wọn lọrun ni orişirişi ọna gbogbo san pupọ-pupọ, o san ni ọna ẹgba ju ẹniti o gbe obinrin kan şoşo ni iyawo ti o si bura niwaju Olodumare ati enia wipe on nikanşoşo ni on yio joko ti lọrun titi ọjọ iku on; lẹhinna ti o tun nle'mu kiri bi obukọ ni kọkọ ati ni ibaba lẹhin obinrin olobinrin, ti o mbimọ ti kole fowo sọ aiya pe on lo bi i, ti o mba ọmọ-ọlọmọ l'ori jẹ kiri, ti o mbere lọwọ aya-alaya wipe "ori lo nfọ ẹ, tabi ọrun lo ndun ẹ ?" ani, ẹniti o fẹ obinrin meji tabi mẹta si gbangba san pupọ ju ẹniti o fẹ obinrin kanşoşo ti olobinrin miran si ra a mu aya rẹ ti o si nrababa nilẹ bi ẹjo wipe bo aşiri yi fun mi—Ọlọrun yio bo ọ laşiri.

Awọn ẹlomiran nsọ wipe awọn Imale le şe şina pupọ, agbere ti o wa larin awọn Kiriyo laiye ti a wa yi kosi larin awọn Imale, bi awọn Kiriyo tilẹ mbo aşiri arawọn nigbati nwọn ba ka arawọn mọ, sibẹsibẹ a le sọ wipe tiwọn fẹrẹ tẹ-iwọn ju ti Imale lọ.

Awọn obinrin onişekuşe tarata ti o mbẹ larin awọn Kiriyo ati Imale, awọn ti nwọn npe ni Alada nla, tani nwọn nfi ada wọn na şa ju, bikoşe awọn Kiriyo afọnufọra; ti nwọn ko ri owo da ni Ş şi, ti nwọn ko ri owo tọju, aya, ọmọ ati awon obi wọn ni ile, ti nwọn ko ri d'aşọ sorun ti Şoti ati bata wọn ko şe ri ko şe fẹku, loju Ibadi-aran, loju Awelọrun ati loju awọn ẹgọ nla-nla ati awọn ẹleyin'ju-ẹgẹ pẹ-pẹ-pẹ!

Bi enia ba fẹ obinrin kan şoşo gẹgẹbi aşa Arede ti awọn Kiriyo wa nko ti o si joko ti i, gẹgẹbi ipinnu ti o mbẹ lori aşa yi, o san o dara pupọ; nitori wahala kekere kọ lo mbẹ ninu ikobinrinjọ; şugbọn Kiriyo melo lo ba njoko ti alarede wọn nikanşoşo nilẹ yi ati ni gbogbo ilẹ awọn enia dudu ti o mbẹ ni agbegbe rẹ?

Apẹrẹ wo tilẹ ni awon mo Keu ja mo mo iwe ju ani awọn Alufa papa fi nlelẹ? Ki a ma şẹşẹ so ti awon mẹmba; Ajọpade ha kọ ni Alfa miran pẹlu mẹmba njo pade arawọn lalẹ ni ile obinrin kanna; ati awọn orişirişi iwa-aitọ ti ọpọlọpọ Kiriyo mbo nolẹ fun 'rawọn, eyiti Jesu-Kristi ko fi kọ ni bẹ.

Ẹsin Musulumi ki işe ẹsin ti enia le fi ọtẹ ilu sin gẹgẹbi awọn Musulumi awọn Musulumi miran ti nşe L'eko loni, a tilẹ ri ka ninu Koran gan pe Ọlọrun ni On ko fẹ tẹmbẹlẹkun larin ile larin, adugbo larin ijọ ati larin ilu.

Emi ko jẹ kirun lẹhin Lemọmu bayi bayi., emi olowo, emi agbalagba; tani Iwọ na, Iwọ, Iwọ to ntapa, to nfọgan si ẹniti o wu Sati lati gbe si ipo na pe o ko jẹ kirun lẹhin rẹ lailai. Iwọ, Iwọ ha tobi ju lati tẹle ilana Anobi Mọmọdu pe ohunkohun ko şẹhin Ọlọrun ati pe amuwa Ọlọrun ni ohun gbogbo laiye ati pe Mọmọdu Ligali ọmọ Lemọmu Nolla ti awọn Jamat Musulumi we Lawani Lemọmu fun ni ọjọ kọkanla oşu November—1923—eyiti o nlọ si iwọn ọdun marun nisisiyi, dipo iku Lemọmu Buramọ ni ọjọ kejidinlogun oşu October ọdun 1923 kanna.

Ki ti ẹsin tun pati sẹgbẹ kan, Kotu Ọba King, Kotu Onidajọ kan, Kotu Onidajọ mẹta gba pe Ligali olohun-iyọ ni a fi jẹ Lemọmu lọna to tọ suna; sibẹsibẹ awọn "Gbẹbọ" fi ake kọ'ri, irufẹ iwa yi dabi iwa Abo Jaili ti o ni lailai on ko ni gba ti Anobi Mọmọdu, ti o ti itori rẹ se ilẹkun Babu—Salami pa ni ilu Mọka pe ki Anobi ma fi le ri aye wọ "Ile Oluwa" lati şe ẹsin rẹ, şugbọn ti Ọlọrun tun fi agbara rẹ şi ilẹkun Ile Rẹ ni ọna bi ogoji fun Anobi Mọmọdu lati sin ẹsin rẹ, awọn ere ti o nlọ si "Hadji" mọ nipa ilẹkun Babu—Salami na, awọn ẹniti o si Keu faufau mọ nipa ohun ti a nwi yi, ki ẹ bi ara nyin lere bi a ba fi nşe abuşọ ni.

Nigbati a ba nri iwa miran ti ko tọ Suna ti Musulumi miran nhu, ti a ba nri obinrin Imale to nyan Kiriyo lọrẹ, ti a ba nri awọn alagidi ati onigirimọkayi diẹ ti o nfẹ jẹ gaba lori gbogbo Musulumi iyoku ni ilu, nitoripe oyinbo npọn si wọn lẹhin nigbagbogbo, ti a ba nri Musulumi to nfi ọti gba'wẹ to nfi Biya sọ'nu, ti a ba nri Musulumi ti inu rẹ ndun nigbati awọn panapana ntu omi si Mọşalaşi, ti a ba nri Musulumi ti o ntọ'ka pe ki nwọn lọ ra lagbaja mu, ti a ba nri Musulumi ti o nşe şina, ti a ba nri Musulumi ti o nba elegungun mu'ti, ti o mba olorişa j'obi, ti a ba nri Musulumi ti o nya wọn ni owo-ele, ti a ba nri Musulumi ti o nhu irufẹ iwa wọnyi ati awọn iwa miran ti ko tọ suna, ero ti o wa si ọkan wa nipe, nibo ni nwọn ma ru u wọ lọjọ idajọ ani lọjọ igbende-alikiomọ.

Şugbọn ọpọlọpọ ọkẹ-aimoye Musulumi lo nşe gbogbo ohun ti Anobi Mọmọdu ko fi kọ wọn ninu oju ọna Islam, gẹgẹbi ọpọlọpọ ọmọ-ẹhin Kristi ti nhuwa ti Bibeli ko fi kọ wọn, ti nwọn si nro wipe şe o di igbati awọn ba de ọrun ki Ọlọrun to da ẹjọ fun wọn, erokero lo mbẹ lọkan iru awọn ẹni bẹ, bi o tilẹ di ọrun ki olukuluku to jihin işẹ rẹ ni aiye, sibẹsibẹ, awa le sọ wipe ko gba Oluwa ni işẹju kan ti o ba nfẹ mu enia ni aiye nihin papa—adura tiwa ni pe ki Ọlọrun maşe mu wa, bi ẹlomiran ba tilẹ nro wipe on ti gun'gi on ti ri ẹhin aiye debi ti ọwọ Ọlọrun ko file tẹ on mọ.

Nipa adura nikan kọ ni a le fi şe Asalatu f'onişẹ Ọlọrun, bikoşe iwa pẹlu, nipa titẹle bibẹru Ọlọrun ti o mbẹ ninu Kuran, nipa titẹle gbogbo ilana Onişẹ Ọlọrun papa, nipa riran ara wa lọwọ nipa didariji awọn ọta wa, ati lai wa işubu tabi ipalara ọmọ ẹnikeji wa, lai şe gbogbo ohun ti a wi wọnyi, kosi ohun ti Ọlọrun yio fi gbogbo Asalatu nyin şe—nitorina ẹ ba wa şe Asalatu fun Onişẹ-Ọlọrun *Salalahu alaihi Wasalam!*

## ELEKO ẸRU ỌBA NI MO BA.

Nipa ọran jijare ti Ọba wa Eleko jare Apili rẹ ni Privy Council, eyiti gbogbo ilu nyọ si ti awọn eniwe-irohin wa si nşe fuja ayọ na le lori—ọrọ pataki ni a nfẹ sọ nipa rẹ loni ri eyiti o yẹ ki a fi dupẹ lọwo sati pe oju ti Alabosi, oşumare jare ojo, şugbọn a tun nwoye arafi oro kan lọwọ, ao fi eyi si igba diẹ, nitorina ki gbogbo nyin si ba wa Yombo On'şẹ-nla na.

Emi ni ti nyin nitotọ,

KEKERE-AWO.

---

Botijẹpe ni akoko' ojo bayi gbogbo oju ọna lodi ari male kọja fun ọpọpọ omi tabi abata, tikojẹ ki enia lekọja ni apa ibomiran, abẹ awọn Municipal lẹbẹ papa, ki wọn jowo ba ni fi oju to ọna Idunmagbo Street ni apa ibi ti o ti wa ja si Princes Street boti bajẹ to ki wọn fi ero si lati ba tun ọna ibẹ na şe fun akoko yi ẹjọwo eşanu ki ẹ ba wa tun ibẹ şe fun alafia awọn ara ilu laipẹ yi. Asi tun ki yin ni pa ti Kereni Idunmagbo papa ari pe o şẹ yọri diẹdiẹ awọn enia nrin oku mọto nikan.

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, JUNE 30, 1928.

## IWE ADEHUN IJỌBA GẸSI PẸLU ỌBA DOSUNMU HA JẸ IWE "ARAMU" BI?

A ti ngbe lọjọ pipẹ lati sọrọ diẹ nipa Iwe Adehun, ti Ọba *Queen* Ijọba Gẹsi ṣe pẹlu Ọba Dosunmu nipa eyiti Eko fi di ti Gẹsi loni; ṣugbọn aye ko si nitori ọro Eleko ti koi ti di dida ni kotu Abẹsẹ Ọba *King* a si tun dupẹ pe ninu eyiti aiye gbọ ti orun si mọ pe Eleko jare, ọrọ ṣi silẹ fun wa lati sọ gbolohun meji mẹta na.

O ti di ohun ti ọmọde tagba mọ pe pataki ohun ti o mbẹ ninu Iwe Adehun ni eyiti a tẹ ẹda rẹ sapakan *Eko Akete* t'oni koju bayi lọ,

*(1)* Ijọba Gẹsi fẹ ki owo ẹru parẹ l'Eko.

*(2)* Ijọba Gẹsi fẹ ki òwò Ọjatita Ọjarira ma gbilẹ.

*(3)* Ki a si dawọ ogun larin orilẹ ede kan si ekeji duro.

A gbọ pe nigbati Iwe Adehun yi ti di fifọwọsi Ọba *Queen* sọpe Ijọba ilu Eko di ti on ati arọmọbọmọ on titi lailai.

A fẹ ki ẹnyin ọkawe ṣakiyesi ọrọ na "ati arọmọbọmọ on titi lailai," Ọba *Queen* si tun sọpe nitori fifọwọsi ti Ọba Dosunmu fi ọwọ si Iwe Adehun yi, on Ọba *Queen* yio ma fun Ọba Dosunmu ni nkan bi ẹgbẹrun (£1000) lọdun lara owo ti Ijọba Gẹsi ba nri l'Eko.

Loju wa Iwe Adehun Aramu ti o tun ju eyi lọ ko si mọ; ki lo tilẹ njẹ "Aramu" gidi? itumọ ti a le lo fun ni nkan ti o ba pakasọ tabi ti o tẹ sapakan tabi ti ko dọgba mọra wọn; njẹ ti o ba jẹ itumọ rẹ leyi a ha le pe Iwe Adehun Ijọba Gẹsi pẹlu Ọba Dosunmu ni Iwe Adehun "Aramu" bi? Ni ti wa Iwe Adehun na papa lo pe ara rẹ ni "Aramu" ki ṣe awa papa, nitoriti ko ba ṣe bẹ ni ki lo ṣe ti a fi ka pe Ọba *Queen* wipe Ijọba Ilu Eko di ti on "ati ti arọmọbọmọ on titi lai"; ṣugbọn nigbati o kan ti Ọba Dosunmu wayi o a sọ pe owo bi ẹgbẹrun poun ni Ijọba Gẹsi yọda fun lọdun lalai jẹ pe owo ọdọdun na yio jẹ ti Dosunmu papa "ati ti arọmọbọmọ rẹ titi lailai" kinṣe ti Ijọba Gẹsi fi ṣe Adehun apakan bẹ fun Ọba Dosunmu gidi? Tabi wọn rope Ọba Dosunmu ko gbọdọ ni arọmọbọmọ ni? Talo gbọdọ ṣe irufẹ Iwe Adehun bayi lode oni ti ki yio di akisa mọ oluwarẹ lọwọ kiakia bi irufẹ Iwe Adehun na ṣeṣi di ẹjọ riro ni kotu; wọn ni amukun ẹru rẹ wọ, o ni ẹ ko wo salẹ; a woye pe rogbodiyan ati aidọgba ọrọ ilu to mbẹ l'Eko ko ṣẹhin aid gba Iwe Adehun ti Ijọba Gẹsẹ ti ṣe pẹlu Ọba Dosunmu lọ; a ba feyi ṣe iwọ, iwọ jẹ fẹ, iwọ jẹ gba? Njẹ bi ẹnikan ba tọka si irufẹ ọrọ bayi ni ilu Ọba ti oluwarẹ si sọrẹ na fun gbogbo aiye gbọ lalai jẹ pe o sọ pe ẹnikan lo ran on njẹ laifi ma leyi? Nigbati Ọba Dosunmu si w'aja nkọ ẽlo ni Ijọba nsan fun Ọba Oyekan a r o l e re? Nigbati Ọba Oyekan si tun w'aja nkọ elo ni Ijọba Gẹsi nsan fun *Prince* Eshugbayi ọmọ Dosunmu Ọba ti o si jẹ aburo Oyekan, o ha ju ọdunrun (£300) poun lọdun bi; Ijọba ṣa wipe "Owo Rẹmilẹkun" (*Compassionate allowance*) ni ọdunrun p ọ u n (£300) ọdọdun na jẹ; lode oni ọgọrọ awọn Akọwe Ọba onipo nla kọ lo ngba ilọpo meji; owo ọdọdun ti Ijọba ti nsan fun *Prince* Eshugbayi Eleko ri? Eku ti o da eyi silẹ lo njẹ ẹda; Ijọba ki yio ha mu ẹtọ kan ṣe si Iwe Adehun "Aramu" yi bi? O to akoko lati pa Adehun yi loku ki Ijọba Gẹsi si ṣẹ atunṣe rẹ.

"Bi yio ṣe'mi
Bi yio ṣe 'wọ
Ni ko njẹ ki a su si oko airoju."

## KINI EWURĘ ŞE?

[ Wosika Lati Ọwọ Atari Ajanaku. ]

Si Oniwe-irohin "Eko Akete,"

Mo bẹrẹ f'oji,

Bi ika ọwọ ko ti dogba jalę, bẹni ipo enia li aiye ju ara wọn lọ, o si şoro pupọ ki gbogbo wa to le ma şe işẹ kanna. Bi gbogbo ilu ba kọ işẹ Dokita, ko si ẹniti yio ri owo fi jẹun ninu gbogbo wọn—bẹni gbogbo wa ko le jẹ Lọya tan, ki a si wipe ẹjọ-ẹlẹjọ şa ni a o ma ro bi igbati obi nku si ọran-ọl'ọran.

A fẹ, a kọ; Kapinta, Telọ, Akowe, Alaru, Onişowo, Agbẹ ni lati wa li arin wa; bẹni a ko le fẹ ẹniti yio ma sin Adię, Tolotolo, Ewurẹ, ati ohun-ọsin miran ku ninu wa.

Ewurẹ jẹ ohun-ọsin pataki fun pupọ ninu awọn arugbo wa; Mọrẹnikẹ nş'oge, Iya rẹ np'afọ bi ẹlẹdẹ-odo, enia pọ to wọbu li Eko. Bi o ba ri iya ẹlomiran ti o we lawani t'o funfun ju yinyin lọ, tabi ti Kọla rẹ ga ju inşi mẹta (3 inches) lọ, oju yio ti o. Eko nikan boya, ni a le ri ọpọlọpọ ọmọ ti ko bikita fun iya wọn—papa bi iya na ba jẹ alaşọ-riro, ọmọ rẹ ko ni fẹ ki ẹnikẹni mọ wipe Iya on li o nşe; bi iya ẹlomiran ba si jaja ni owo l'ọwọ diẹ—adura ki o ku, ki o ku, ni ọmọ rẹ yio ma şe ni ojojumọ, nitori ati ri ogun jẹ.

Ninu ikoko dudu ni ẹkọ funfun ti njede; ọmọ-k'ọmọ, iba şe ọkunrin tabi obinrin ti o ba si ntiju, tabi ti ko bikita fun iya rẹ, nitoripe on jẹ gbajumọ ati wipe iya on na jẹ mẹkunnu Olorun, ti ko si bu ọla fun baba rẹ, irufẹ ọmọ bẹ nfi a-da-bi ti o buru ju epe lọ ş'ere ni: nikẹhin ni yio si mọ wipe, a ko ri ẹbọ abamọ şe.

Njẹ ko ha yẹ ki irufẹ iya ti ko ni olutọju bẹyi, ti o si ti d'agba ju ẹniti awọn boys le şẹju si, wa ohun ti yio şe fun onjẹ-ọjọ rẹ? Tabi tani le kilọ fun u wipe ko gbọdọ sin Ewurẹ, ti a le ma ko ọmọ rẹ ta li ọdọdun ni Ọbun-Eko? Ẹniti o ri nkan jẹ papa nsin Ewurẹ, ki a ma şẹşẹ sọ ti ẹniti ko jẹun ana (yesterday) sun.

Şugbọn ati sin Ewurẹ ko to ati ri owo san lati fi gba a nigbakugba ti awọn Ọmọ-eriwo ba mu u.

Ọpọlọpọ ni ko mọ ohun ti Ewurẹ şe, ti o fi di ọta Oyinbo. Kini Ewurẹ şe? Ẹnikẹni, ti Ewurẹ ba gbe oni-kẹkẹ ologere, bi Basikulu (Bicycle) tabi Motọ-ka (Motor-cars) papa şubu l'oju rẹ lẹkanşoşo, yio mọ ohun ti Ewurẹ şe ti o fi di ọta Oyinbo. Fun anfani awa papa, ewu pupọ li ọ wa ninu ki Ewurẹ ma jẹ li ọna awọn Opopo-nla, bi Ẹhingbẹti, Ẹhin-ọgba ati Titi (Streets) miran ti o tẹju gbalasa; nitorina, Ewurẹ-k'ewurẹ ti o ba jẹ l'arin awọn Opopo-nla wọnyi, nkan-ki-nkan ti o ba ri nibẹ, ko nşe ẹjọ ẹnikan.

Eyiti ko ye wa rara nibẹ, ni ki nwọn ma mu Ewurẹ ni ọdẹdẹ oluwarẹ, tabi kakiri kọrọ adugbo miran ti Motọ ko nsaba gba nigbagbogba, gẹgẹ bi a ti ngbọ. A si tun gbọ ẹwẹ wipe, ọpọlọpọ enia ti nwọn mu Ewurẹ wọn ni ko tun nri wọn gba pada mọ, bi nwọn tilẹ mu owo lọ si ibiti a ko wọn si; o yẹ ki Ijọba tabi awọn Munisipa (Municipal Dept.) kilọ daradara fun awọn ti o nko Ewurẹ kiri, ki nwọn maşe mu Ewurẹ li ọdẹdẹ oluwa rẹ, ki nwọn si fi awọn Ewurẹ ti o njẹ ni kọrọ adugbo ke-ke-ke silẹ ni alafia, ki diẹ ninu awọn arugbo wa le ma ri owo i-da-'kọ-mu ni ararọ

Ninu gbogbo ofin Ijọba tabi ofin ilu, ko yẹ ki a gbagbe talaka; talaka li o pọju ni ilu: li aisi wọn, ẹwẹ, kini olowo le şe?

Emi ni ti nyin nitotọ,
ATARI AJANAKU.


## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oşupa mi" jẹ oju-lowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le şẹşẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Şango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Orişi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Şabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maşe gbẹhin ki ẹ to ranşẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

## Olusakin's Column.

PRIVY COUNCIL APPEALS.

Under the above heading the popular London Weekly paper *West Africa* of the 26th May, 1928, which reached this port by the *T.M.V. Adda* on Thursday last, the 21st instant, contained the following passage :—

" Our news columns to-day contain full reports of the Privy Council judgments in the Macauley and Barrett cases. That on the Eleko case is due at an early date and is eagerly awaited. In the meantime I learn that the following passage, in a speech by the Lord Chancellor in the House of Lords, relates to that case, which was the only one heard by him on the day referred to :—

" He had that day been hearing in the Privy Council a case raising difficult and important questions as to the liberty of the subject. They would pronounce a decision which would probably guide all the tribunals in the country on that point, and which would, therefore, in a sense, affect perhaps the rights of the public for all time to come. Similarly, any decision which was given by the Court was given without anyone except the parties knowing that the point was being argued, and without any opportunity to anyone else to intervene, and submit his point of view. Yet the decision, once given, remained binding on the whole country, and remained the authority which guided all courts of co-ordinate or inferior jurisdiction. "

PROMOTION.

Mr. Benjamin Ọbafunmi Taylor, Assistant Chief Clerk, Nigerian Railway Accounts Department, Ebute Metta, has been promoted to the rank of an Assistant Accountant, as from the 30th April, 1928.

Mr. Taylor joined the Railway Service on the 3rd February, 1905. Congratulations. Hats off to the Chief Accountant, Nigerian Railway.

ARRIVAL.

The Venerable Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi and delegates who left Lagos on Tuesday, the 12th June, 1928, to Sapẹlẹ by special request of the Honourable Mr. I. T. Palmer, inviting the Archdeacon to preach at Bishop Johnson's Memorial St. Luke's Church, Sapẹlẹ, which was recently built, arrived Lagos on Wednesday, the 27th instant.

*Ẹ ku abọ, alafia kẹ de bi, ọhun ko dun bi ?*

BIRTH.

We congratulate Mr. and Mrs. Olufọla Sapara of 41, Broad Street, Lagos, for the gift of a male child, on Wednesday, the 20th June, 1928. It is reported that both mother and child are doing well.

To Dr. Oguntola Sapara, I.S.O., the Grand-Papa.

*A ba ọ yọ, ki Oluwa da ọmọ si.*

THE COLONY.

**Income Tax (Colony) Ordinance, 1927.**

IS MIGHT ALWAYS RIGHT? NO!

It is understood that Government Officials were short paid this month the shortage being a compulsory deduction from their salary to satisfy the whims and caprices of the local Income Tax Ordinance. In the case of the Nigerian Railway African Staff, we understand that the deduction was made in a bulk contrary to the express wish of many of those concerned, to say nothing of those who maintain an uncompromising attitude towards the obnoxious measure in view of its redundancy at present and consequent unjustifiability.

TRINITY EXAMINATION BAR FINAL RESULTS

The Council of Legal Education announcing the results of the Trinity examination of students of the Inns of Court held on May 17, 18, 19, 21 and 22.........In the Bar final Mr. Edward Kofi Bossman passed in Class II, and Messrs. Richard Adeẹyọ Doherty and Francis Edney Olude Euba in Class III.

*West African 19/6/28.*

Mr. Olude Euba is the third son of the Rev. W. B. Euba. Congratulations.

OLUṢAKIN.

"TẸMBẸLẸKUN ỌTẸ ẸTU BIBUINA SI NI NIGERIA."

AMI ERU.

Agbọsọ na ngbilẹ pe awọn okumarata enia kan ngbero ati ṣoju Moto Ọba ti *Prince* Eshugbayi Eleko yio wọ lati Ọyọ wa silẹ yi de, ati pe awọn kan npete ati fi owo bẹ mọṣaṣi enia kan lọwẹ lati yinbọ fun Ọmọ Alade na ninu Mọto ti yio wọ wa

Eko, ki Eleko ma ba le de si Eko bi o ti wu ki o ri.

A tẹ a gbọ sọ yi fun awọn Alabojuto Ọlọpa Inu lati ri ka nitoripe "Igi ganganran ma gun mi loju okere lati mbẹrẹ."

Awa ko sọ ohun ti ko si tabi ti yio gbe ọkan enia soke şugbọn o jẹ işẹ wa lati tẹ ohun ti a ba gbọ.

*Translated from Lagos Daily News 2/6/28.*

---

IPADE NI ILE ỌBANIKORO, OLOYE.

Oloye Ọbanikoro (Adamo Akẹju) pe apejọ kan si ile rẹ ni agogo mẹsan abọ alẹ ni ọjọ Alaruba ni Idoluwo; a si so pe pupo ninu awọn enia tirẹ ni nwọn wa ni Ipade na pẹlu Oloye Ọjọra, Oloye Onitana, Oloye Oniru, ati Oloye Omidiji awọn ti nwọn jẹ ti Ibikunle, Karimu Kọtun ati awọn miran.

Ninu ọrọ ti nwọn sọ nibẹ ni a sọ pe Oloye Ọbanikoro ba wọn sọrọ bayi:

Nipa ti pipe ti Ijọba pe wa lọ si ibi işẹ Sẹkitẹri agba lana, o jẹ nipa ti pipadabọ ti Prince Eşugbayi Eleko yio pada wa si Eko, Ijọba ni awọn ko fẹ rudurudu kan tabi ija tabi ariwo ija kan-kan rara ni Eko ni ọjọ ti Prince Eşugbayi Eleko yio pada bọ wa si Eko, Ijọba sọ wipe o da won loju pe awọn ilu (eyini ni awọn ọgọrọ enia) ki yio ja tabi ki nwọn şe rudurudu kan ni ọjọ na nitoripe o daju pe inu wọn yio dun ni ọjọ na nwọn yio si ma jo mukulu-mukẹlẹ kakiri ilu, pe nigbati nwọn fi mu Prince Eşugbayi Eleko lọ ni August 1925, awọn enia wọ yi ko pariwo ija tabi rudurudu kan ni ilu. Nitorina mo ni lati so fun gbogbo nyin pe ẹnikẹni ninu nyin ko gbọdọ şe nkankan ti yio da rudurudu silẹ lọjọ na.

Emi nşe kilọkilọ yi fun gbogbo nyin nisisiyi pe ki olukuluku joko si ile rẹ ni ọjọ na, ti ẹ ba si pada lọ si ile laleyi ki ẹ fa awọn ọmọ nyin ati awọn iranşẹ nyin leti ati gbogbo ile nyin nipa ọrọ yi.

Ẹnikẹni to ba si ja tabi to da ija silẹ ni ọjọ na: Ijọba yio kọngọ fun oluwarẹ ti owọ ba tẹ ẹ, ki eku ile wi fun ti oko nipa ikilọ yi o.

Ẹnikan ti o njẹ Karimu Kọtun wa dide a si jihin pe, o sọ bayi pe "nigbati enia ba nlọ si ogun ma-mu ma-pa, ni oluwarẹ mba lọ, ọhun ni ikẹta nde ba a," gẹgẹ bi a ti wa ni ibi ni alẹ yi ikẹta ba wa nisisiyi bo şe ti emi ni emi yio şe itọju ara mi ngo si fi ọrọ ti Oloye ba wa sọ ni alẹ yi si ọkan. Imọran mi si gbogbo awa ti a wa nibi lalẹ yi ni pe ki olukuluku şe gẹgẹ bi Oloye ti wi. Lẹhin igbati nwọn fi enu ba ipanu ti Oloye na ti fi de wọn, Ipade si tuka.

*Translated from "Lagos Daily News" 29/6/28.*

## LASIGBO AIYE.

Ọpọlọpọ adura lo yẹ ki gbogbo Ilu tẹwọ nisisiyi fun ọda owo ti o d'ode; irufẹ ọda na ti wa ki ş'aruwa: ebi mbẹ nilu, ọda-işẹ mbẹ nibẹ, Oyinbo-Onişowo nke; Lọya nke, awọn Akọwe nke, awọn enia wa Onişowo nke; awọn obirin alata oniyọ nke; ewo ni şişe? Ile aiye ko şe gbe Alijanna ko şe lọ, ọna 'o pe mẹta ewo la o şe? Ọgọrọ Bọkinni miran lo ji ti awọn ko b'ẹgba ji, bẹ ifun ko ni şai gba "ẹbọ", rẹ orọ: orişa bi ifun kosi ojojumọ lo ngb'onjẹ: igbese ni on ni igbese; nigbati ko ba si loju, ki lo mọ kan saiya? Igiripakọrin miran wa bale ile ti o nwa ẹkun mu nigbati o ji laro ti o nronu kọbọ ti on yio fun ọmọ rẹ lati ra "bẹrẹdi": bẹ Ọgbẹni ti kirikiri pẹlu Iwe-işẹ wiwa, ti eşinşin ko kun u: o ha ni ya ẹnikẹni lenu lati gbọ pe Gbanjo omiran nkun fun oku Coat, oku Shirt, oku Şokoto ati oku Bata, fun titi lati ri okan, eji jẹun: abuşọ ko si ninu eyi, bi enia ba bi awọn Onigbanjo miran, nwọn yio sọ lai darukọ ẹnikankan: owo ile hihaya şẹ si ẹlomiran lọrun; ko ha ni şẹ: nigbati ko si işẹ nkọ, kini oluwarẹ yio fi sanwo ile, bẹ irufẹ ẹni bẹ ko ni sun si ita gbangba, bẹ si ni ko ni sun s'abẹ pẹnu Ita Faji. B'oku fẹ bi ko fẹ, ẹ ko wo ọmọ oloku lode: bi ọrọ ti a ti nsọ yi ri bẹ, a fẹ ki ẹnyin okawe wo bi ode tiri nisisiyi.

Gbogbo aisişẹ, aisowo nilu wọnyi gejia ẹnikẹni; ọna wo la gba? Njẹ bayi ni ara yio ma kan ilu gogo titi? Ẹnyin Alaşẹ Ilu, ẹnyin Agba Ilu, ẹ da ro. Ninu Iwe-asọtẹlẹ Eko ti *Carpricornus* şẹ f'ọdunni o sọ pe owo yio ya yẹyẹ lọdunni: şugbọn sibẹsibẹ koko bi oju ẹja ni gbogbo nkan ri, eyi ti jẹ? Kosi nile, kosi l'oko.

Ki Baba ma şai f'oju anu Rẹ wo Ilu Eko yi ki o si fi ibukun atokewa Rẹ jinki olukuluku wa.

BANUSỌ.

---


## KERE O!

Mr. C. B. SHODIYA, *Produce Buyer*, ti No. 132, nitosi Niger Company, Ebute Ero, ni ọpọlọpọ Tapo (Tapaulin) siye 15 x 15 fun hihaya, bi o fẹ şe ariya ti Iyawo lọ sibẹ, bi o fẹ şe Wolimọ lọ sibẹ, bi o fẹ şe ariya nipa ti oku lọ sibẹ, o wa fun ẹnikẹni ọpọku-ọyọku ni owo hihaya rẹ.

ọd. ẹgbẹdogun fun Tapo kan lojumọ.

C. B SHODIYA,
*Produce Buyer*,
132, Ebute Ero,
Marina, Lagos.

## We are sole local Agents for

# Vibrona

*The Ideal Tonic Wine.*

SURPASSES ALL OTHER WINES

AS A

## TONIC STIMULANT

AND

## INVIGORANT.

**VIBRONA** has been justly described as the **Supreme Tonic,** and the world-wide reputation which it enjoys is mainly due to the personal testimony of those who, having experienced its remarkable energising powers, are glad to recommend it to their friends.

A liqueur-glass of VIBRONA, taken either alone or with a plain biscuit, is almost magical in its effect as a Tonic Restorative.

The modern Discovery for Female sufferers is

## Wireless Female Pills

A sure remedy against all kinds of monthly disorders experienced by women, and an effective vitaliser against harreness. 4/6 per bottle of 72 Pills.

## Kaduna Balm 1/-

The family Remedy applicable in 100 different ways. Indispensable during this rainy season.

## Saccharine 1/-, 1/6

## Anti-Rhumatic Salt 2/- and 3/6

## Rheumatism Pills 1/6

## Yaro (*small and large*) 2/3 & 3/3

## Pile Pills 1/6

## Pile Remedy 7/6

## Cooling Blood Purifier 7/6d.

(A powerful blood cleansing Preparation).

## Gonorhea Remedy 7/6 & 4/6.

Works with effective rapidity.

***Dr. De Roos' concentrated Guittae Vitae for general Debility, shaking of the hands and limbs, dimness of sight &c., miraculous curer, largest size £2. 2. 0.***

Special Wholesale Price.

*Obtainable at:—*

# IYIN OLUWA MEDICINE STORES

*Head Office:*—88, Broad Street, Lagos,
*Branches:*—6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
109 Griffith Street, Ebute-Metta.

# Advertisement.

Vacancies occur at Ijora and other Stations in Nigeria for a number of experienced boiler house engine from attendants.

Applications will only be considered from men having previous experience with high pressure boilers and high speed reciprocating steam engines.

Commencing Salary from £72 to £88 per annum, according to qualifications.

Full particulars of experience and training should accompany applications, which should be in writing and addressed to the Director of Public Works, Lagos.

---

# Attention! Attention!! Attention!!!

FOR BUYERS IN GENERAL.

HAVE YOU BEEN AT

## IWA-JO-WA STORE, (No. 1 & No. 2)

IF NOT, WHY NOT? AN OPPORTUNITY ONCE LOST CAN NEVER BE REGAINED.

The undersigned have in Stock for sale at unbeatable—prices not obtainable else-where.

The following cheapest materials are kept in Stock.

**Rubby, Rubby, Rubby!**

*( Again and again, "Gbangba dẹkun" Kedere bẹ wo. )*

**Goldsmith Tools :—**

Pickers, of any kind or size
Plowpipes, of any kind or size
Scissorses, do.
Drawplates, do.
Brass mouldings, do.
Hand Scale, do.
Brass Lamps, do
Screw Plates, do.
Cutting and doming punches of any kind or size.
Assorted kinds of Files,
Bellows of any description

Bench Vices, of any description
Crusibles, do.
Kegs of saltpetre,
" " Alum,
" " Borax
Pure Silver grains, too numerous to mention.
Capentory Tools of any description
Shoemakers, do.
Sawyers, do.
Bricklayers tools of any description
Bicycle accessories do. etc. etc.
Seeing is believing;

*" Ganni ya fi ji."* Irohin ko to afojuba.

Apply to Proprietors D. ODUSANYA & BROS.,
*Expert Goldsmiths.*

45, Princes Street, Isalẹgangan, Lagos,
20, Victoria Street, Lagos.

*Cable Address :—*
Iwajowa Store No. 1,
45, Princes Street, Lagos.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq., *The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

RẸMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.
*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Paintull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B:—Not obtainable elsewhere.*

GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati orişirişi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
Postage 2/6 extra.

WHITE'S

## WONDERFUL BRAIN TONC.

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq
41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe şişẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba ṣe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
VICTOR WHITE, ESQ, *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.
*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oṣu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aṣẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

# HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to:—

MR. MOSES O. COKER,

Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
(Manchester) Limited,
65, George Street,
Manchester.

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

*Cable Address*:—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIRẸMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets.
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines

Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

# TO LET.

**One Splendid Pleasure Car**

No. L2754.

***Always at everybody's service at Tinubu Square.***

For Terms, Apply to:—

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

# ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

## Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

—— : o : ——

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmini ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ loriṣiriṣi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

**Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.**

Pọ ọ si ni owo wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.